# Olùkùmi: Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá Láàrin Àwọn Èdè Mìíràn Ní Ìpínlẹ̀ Delta

**Alimot Ẹlẹ́shin Ajíkòbi**
*Department of Linguistics, African and European Languages,*
*Kwara State University, Malete*
*limsheen.8@gmail.com*

## Àṣamọ̀

*Olùkùmi jẹ́ ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí à ń sọ ní apá kan ìpínlẹ̀ Delta, òun sì ni iṣẹ́ yìí dálé. Èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni láti fi ojú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wo Olùkùmi (tí à ń sọ ní apá kan iwọ̀-oòrùn gúsù ilẹ̀ Nàìjíríà) kí a sì pín in sí ìsọ̀rí tí ó tọ́ lábẹ́ ọ̀wọ́ ẹ̀ka-èdè Yorùbá (tí à ń sọ ní ilà-oòrùn gúsú Nàìjíríà) láti ṣe àtúnṣe sí ìpín-sí-sọ̀rí asọ̀bátan tí ó pín ẹ̀ka-èdè náà sí èdè ọ̀tọ̀ gédéńgbé lábẹ́ Yoruboid. Èyí jẹ́ ìdáhùn sí ìpè àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè bíi Olúwadọrọ̀ àti Abíọ́lá (2016:334). Ìlànà ìṣàpèjúwe ni a gùn lé láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àbùdá tí ìpèdè méjèèjì ní láti pín Olùkùmi sí ìsọ̀rí tí ó yẹ lábẹ́ èdè Yorùbá. Ìbáṣepọ̀ tí ó wà nínú ìtàn orírun Olùkùmi àti ẹ̀yà Yorùbá, pẹ̀lú àbùdá tí ẹ̀ka-èdè náà ní nílànà ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè jẹ́ kí ó yé wa pé láìṣe àníàní, kò sí bí èdè méjì ṣe lè ti pínyà pẹ́ sí tàbí kí wọ́n jìnnà síra sí, àgbọ́yé yóò ṣì wà ní àárín wọn.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Yorùbá, Olùkùmi, èdè, ẹ̀ka-èdè, àgbọ́yé.

## Ìfáárà

Àwọn alákòóso tí ó ń rí sí ìpín-sí-sọ̀rí èdè (onímọ̀ ẹ̀dá-èdè) lè fi síbì kan lórí fífún èdè kan lórúkọ nípa lílo àwọn àbùdá tí kò jẹ mọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè láti pín in. Ojú àbùdá mìíràn yìí lè jẹ́ yálà ètò-ọ̀ṣèlú, ètò ọrọ̀-ajé, ètò ẹ̀sin tàbí òmíràn. Lóòótọ́, kò sí elédè kan tí ó fẹ́ kí òmíràn jẹ gàba lé ti òun lórí àmọ́, a ní láti mọ̀ pé, bí a bá fi àbùdá tí ó yàtọ̀ sí ajẹmọ́ ìmọ ẹ̀dá-èdè pín èdè kan sí ìsọ̀rí, kò sí kí irú àtúnpín-sísọ̀rí bẹ́ẹ̀ má mẹ́hẹ. Kódà, ó ti ṣe okùnfà pínpín ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ìpèdè tí ó yẹ kí ó jẹ́ ẹ̀ka lábẹ́ èdè kan, sí èdè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ gédéńgbé (b.a Yorùbá àti Itsekiri (Lloyd 1954; Omamor 1976), *Serbian* àti *Croatian* (Edward 2010). Ohun ti Lloyd (1954) sọ nípa Yorùbá ati Itsekiri gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú Adeniyi (2005) ni pé

> In a list of over 100 common words (of Itsekiri) over 90% are almost identical with Yorùbá words especially those of the south eastern dialects.
>
> Nínú àtòjọ ẹyọ-ọ̀rọ̀ (Itsekiri) ti ó lé ní ọgọ́rùn-ún (100) ìdá àádọ́rùn-ún (90%) ni wọ́n fẹ́rẹ̀ jọ ọ̀rọ̀ Yorùbá pàápàá jùlọ ẹ̀ka-èdè tí wọ́n ń sọ ní gúsù-ilà-oòrùn.

Ní ti Omamor (1976), òún wí pé;

> From a purely linguistic point of view, Itsekiri does not seem to be a different language (in relation to Yorùbá), but it is less closely related to the Yorùbá cluster as a whole ...

> Bí a bá fi ojú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wò ó, Itsekiri kì í ṣe èdè tí ó yàtọ̀ (sí Yorùbá), amọ́ agbègbè tí ó wà jìnnà sí àwùjọ tí Yorùbá ṣùjọ si ...

Nípa ti *Serbian* àti *Croatian*, ohun ti Edward (2010) sọ ni pé ìjọra tí ó wà láàrin èdè méjèèjì yìí pọ̀ tó bẹ́ẹ̀ tí ó yẹ kí a kà wọ́n sí ẹ̀ka-èdè èdè kan ṣoṣo, àmọ́ nípa lílo àbùdá mìíràn tí í ṣe ètò-òṣèlú, èdè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a kà wọ́n sí. Ọ̀rọ̀ rẹ̀ lọ báyìí:

> ...forms that are mutually intelligible can be considered as separate languages for purely political reasons. Such is the case of Serbian and Croatian in the former Yugoslavia. The similarities between the two prompts the term 'Serbo-Croatian' by linguists for the two languages. The speakers (Serbs and the Croats) have deliberately invented separate literary standards to render the forms more divergent than they really are.

> ...nípasẹ̀ ètò-òṣèlú, a lè rí àwọn ìpèdè tí àgbọ́yé wà láàrin wọn gẹ́gẹ́ bi èdè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Èyí ni ó ṣẹlẹ̀ sí èdè *Serbian* ati *Croatian* ní ìlú *Yugoslavia* ti tẹ́lẹ̀. Ìjọra tí ó wà láàrin àwọn méjèèjì ni ó jẹ́ kí àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè máa pè wọ́n ní *'Serbo-Croatian'*. Àwọn elédè náà (*Serbs* àti *Croats*) ní láti yan àkọtọ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ fún àgbékalẹ̀ wọn, láti ya ìpèdè náà sọ́tọ̀ ju bí wọ́n ti wà lọ.

Àkíyèsí nípa èdè àti onírúurú àbùdá tí a fi ń pe ìpèdè kan ní èdè, tí a sì kà omiran sí ẹ̀ka-èdè yìí ni yóò jẹ́ kí a ṣe àgbéyẹ̀wò èdè àti ẹ̀ka-èdè gẹ́gẹ́ bi kókó pàtàkì nínú iṣẹ́ yìí.

## *Èdè àti ẹ̀ka-èdè*

Onírúurú onímọ̀ ni wọ́n ti gbìyànjú láti sọ ohun tí èdè àti ẹ̀ka-èdè jẹ́ ní àgbáyé. Lára wọn ni a ti rí Chambers àti Trudgill (1998) tí wọ́n sọ pé;

> Dialects can be regarded as subdivisions of a particular language and a language is thus seen as a collection of mutually intelligible dialects.
>
> A lè ka ẹ̀ka-èdè sí àtúnpín èdè kan pàtó, nípa báyìí èdè jẹ́ àkójọpọ̀ ẹ̀ka-èdè tí àgbọ́yé wà láàrin wọn.

Ohun tí Waudaugh (2010) náà sọ kò sé kò yá sí tòkè yìí. Òún sọ pé:

> Language is used to refer either to a single linguistic norm or to a group of related norms, and dialect is used to refer to one of the norms. A language then would be some unitary system of linguistic communication which subsumes a number of mutually intelligible varieties.
>
> À ń lo èdè láti tọ́ka sí yálà ìpèdè ajẹmọ́ ẹ̀dá-èdè kan tàbí àkójọpọ̀ àwọn ìpèdè tí wọ́n jọra, bẹ́ẹ̀ sì ni ẹ̀ka-èdè jẹ́ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìpèdè yìí. Nípa báyìí, èdè yóò jẹ́ ọ̀kan gbòógì nínú ọ̀nà ìgbà-bánisọ̀rọ̀ ajẹmọ́ ẹ̀dá-èdè tí ó ṣe àkóónú ogunlọ́gọ̀ ẹ̀ka/ìpèdè tí àgbọ́yé wà láàrin wọn.

Àwọn onímọ̀ èdè Yorùbá náà kò gbẹ́yìn nínú fífọ àfọ̀fún lórí ohun tí èdè àti ẹ̀ka-èdè jẹ́. Olumuyiwa (1994:2) sọ pé, 'Ẹ̀ka-

èdè jẹ́ ẹ̀ka kan lára èdè àjùmọ̀lò àwọn ẹ̀yà kan tí okùn èdè so pọ̀.' Ohun tí (Awobuluyi 1998:1) sọ nipa ẹ̀ka-èdè lọ báyìí:

> Ẹ̀yà èdè kan tí wọ́n ń sọ ní àwùjọ kan ni ẹ̀ka-èdè…. Irú àwùjọ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ara àwùjọ ńlá mìíràn tí èdè kan papọ̀.

Adéníyì (2005:25) náà kò ṣàì ṣàlàyé ohun tí ẹ̀ka-èdè jẹ́. Ní èrò ti rẹ̀;

> Ẹ̀ka-èdè jẹ́ ẹ̀dà-èdè ńlá kan (tàbí ọ̀nà ìgbà-bánisọ̀rọ̀) tí àwọn àdúgbò kan ń ṣe àmúlò rẹ̀ láti fi gbé èrò ọkàn wọn jáde tí ó yàtọ̀ sí ọ̀nà ìgbà-bánisọ̀rọ̀ tí àwọn àdúgbò mìíràn tí gbogbo wọn jọ wà ní agbègbè tàbí ẹkùn kan náà, ṣùgbọ́n tí àwọn ará àdúgbò méjì yìí (tàbí ju bẹ́ẹ̀ lọ) gbọ́ ara wọn ní àgbọ́yé. Ẹdà-èdè tí àdúgbò kọ̀ọ̀kan ń sọ yìí sì ní àwọn àbùdá fonọ́lọ́jì, ìhun gírámà àti pípe ọ̀rọ̀ tí ó yàtọ̀ sí ti ẹ̀ka-èdè mìíràn.

Ní ti Ayeomoni (2012),

> A dialect is a distinct form or a variety of a language; it is associated with a recognisable regional, social or ethnic group, different from other forms of the language by specific linguistic features such as pronunciation, vocabulary, grammar or any combination of these.
>
> Ẹ̀ka-èdè ni ìpèdè àrà ọ̀tọ̀ tàbí ẹ̀yà èdè; tí a mọ̀ mọ ẹkùn, àwùjọ tàbí ẹ̀yà kan, tí ó yàtọ̀ sí ẹ̀yà tó kù nínú èdè náà lábùdá ìmọ̀ ẹ̀dá èdè bi pípè, ẹyọ-ọ̀rọ̀, gírámà tàbí àlòpọ̀ èyíkéyìí nínú won.

Ohun tí gbogbo àwọn onímọ̀ yìí ń sọ ni pé, èdè jẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láwùjọ. Òun ni àkójọpọ̀ ìró ohùn tí ó ní ìtumọ̀ láàrin olùsọ àti olùgbọ́. Ó jẹ́ okùn ẹ̀mí àwùjọ torí òun ní ó ń mú ìbáṣepọ̀ tó yè kooro wà láàrin ẹ̀dá ènìyàn tí wọ́n lè sọ, tí wọ́n sì lè gbọ́ èdè. Ẹ̀ka-èdè sì ni oríṣiríṣi ọ̀nà tí èdè kan lè pẹ̀ka sí nípa agbègbè tí wọ́n ti ń sọ ọ́. Ìyàtọ̀ díẹ̀ máa ń wà ní àárín àwọn ẹ̀ka-èdè yìí ṣùgbọ́n àgbọ́yé tí ó pa wọ́n pọ̀ ni ó jẹ́ kí a kà wọ́n sí èdè kan ṣoṣo bíi ti èdè Yorùbá. Àwùjọ àwọn ẹ̀yà tí ó ń sọ èdè kan ni a ti máa ń rí àwọn ẹ̀ka-èdè irú èdè bẹ́ẹ̀, èyí ni ó fà á tí ó fi jẹ́ pé Ìwọ̀-Oòrùn Gúsù orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni a ti rí àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá bi, Ẹ̀gbá, Èkìtì, Ọ̀wọ̀, Ọ̀yọ́, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀ṣà, Ìgbómìnà, Ìlàjẹ, Ìkálẹ̀, Mọ̀bà, Owé, Yewa, Yàgbà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Orúkọ agbègbè tí wọ́n ti ń sọ ẹ̀ka-èdè wọ̀nyí ni orúkọ èdè tí wọ́n ń sọ ní irú agbègbè bẹ́ẹ̀ sábà máa ń jẹ́. Bí àpẹẹrẹ, Ọ̀wọ̀ àti àwọn agbègbè bíi Uté, Èchò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n ti ń sọ èdè Ọ̀wọ̀. Ọ̀yọ́, Fìdítì, Ìbàdàn àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ ni wọ́n ti ń sọ èdè Ọ̀yọ́. Ìjẹ̀ṣà ni wọ́n ń sọ ní ìlú Iléṣà bí wọ́n ṣe ń sọ Ìjẹ̀bú ní àwọn ìlú Ìjẹ̀bú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí kò túmọ̀ sí pé ilẹ̀ Nàìjíríà nìkan ni wọ́n ti ń sọ èdè Yorùbá torí àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè àti àwọn onímọ̀ ìtàn sọ pé àwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá kọ̀ọ̀kan máa ń jẹyọ nínú èdè àwọn ẹ̀yà kan ní Cuba tí wọ́n ti ń pe ẹ̀yà tí wọ́n ń lò ní Lukumí[1], ilẹ̀ olómìnira Bìnì tí ó ti ń jẹ́ Ànàgó, Sierra-Leone tí ó ti ń jẹ́ Akú, Togo tí ó ti ń jẹ́ Ifẹ̀-Tógò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

1. Èyí ni èdè tí àwọn ọmọ apá ìwọ̀-oòrùn ilẹ̀ adúláwọ̀ tí a kó lẹ́rú lọ sí Cuba máa ń lò fún ìjọ́sìn, tí wọ́n tún ń pè ní Regla de Ochá tàbí La Regal de Lukumí.

Títa kété tí Olùkùmi ta kété sí àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá tó kù nílẹ̀ Nàìjíríà, nípa fifi apá ìlà-oòrùn ṣe ibùjókòó, nígbà tí àwọn ọmọ ìyá rẹ̀ tó kù wà ní apá ìwọ̀-oòrùn tọ́ ní gbígbé yẹ̀wò. Èyí sì ni ó ṣe okùnfà iṣẹ́ ìwádìí tí a gbé kalẹ̀ ní ìlànà ìṣàpèjúwe yìí.

Nínú iṣẹ́ yìí, a rí ẹ̀ka-èdè gẹ́gẹ́ bí ìpèdè kan tí àgbọ́yé wà ní àárín rẹ̀ àti ìpèdè mìíràn láìfi ti ìyàtọ̀ kọ̀ọ̀kàn tí ó lè wà nínú ipele ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wọn (bíi ìpè ọ̀rọ̀, ẹyọ-ọ̀rọ̀, ìhun gírámà) tàbí agbègbè tí wọ́n wà ṣe.

**Olùkùmi àti àwọn tí wọ́n ń sọ ọ́**

Ìwádìí fi yé wa pé Olùkùmi jẹ́ àpólà orúkọ tí ó túmọ̀ sí 'ọ̀rẹ́ mi' nínú àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá bíi Ifẹ̀, Ọ̀wọ̀, Owé àti Ìtsẹ̀kírì pẹ̀lú Ìgalà tí wọ́n jẹ́ èdè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ lábẹ́ àwọn èdè tí wọ́n jùmọ̀ jẹ́ *Yoruboid* lórí àtẹ Ìpín-sí-sọ̀rí Asọ̀bátan. Apá Àríwá ìjọba ìbílẹ̀ Aniocha ní ìpínlẹ̀ Delta, tí à ń pè ní ìran *Odiani* ni wọ́n ti ń sọ èdè yìí. Àwọn agbègbè tí ó wà lábẹ́ ìran yìí tí wọ́n sì ti ń sọ èdè náà ni: Ugbódù, Ukwu-Nzu, Ogodor, Ubulubu, Ugboba, Idumogo àti Anioma. Ugbódù àti Ukwu-Nzu gan-an ni wọ́n ti ń sọ ọ́ ní pàtó. Àwọn tí wọ́n ń sọ ọ́ ní agbègbè tó kù ṣí láti yálà Ugbódù tàbí Ukwu-Nzu lọ sí ibẹ̀ ni. Àwọn tí wọ́n ń sọ Olùkùmi jẹ́ kí ó yé wa pé ilẹ̀ Yorùbá ni àwọn ti ṣí lọ síbi tí àwọn wà lónìí. Èdè yìí ni ó ya àwọn olùsọ rẹ̀ sọ́tọ̀ sí àwọn ẹ̀yà Igbo ati Ishan tí wọ́n yí wọn ká. Èyí ni ó mú àwọn onímọ̀ kan bi Maher (1996) pe ìran náà ní*'Yoruba Enclave'*. Láti ní

àforísọ kan gbòógì, ẹ̀yà tí wọ́n ń sọ ní agbègbè Ugbódù ni a gbé iṣẹ́ yìí lé lórí.

### *Àpèjúwe ìlú Ugbódù*

Bí ìgbín fà ìkarahun á tẹ̀le ni ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin àyíká àti ìmọ̀-ìtàn jẹ́, èyí ni yóò sì jẹ́ kí á ṣe àpèjúwe ibi tí à ń pè ní Ugbódù ní ìpínlẹ̀ Delta, fún ànfàání àwọn tí kò dé ibẹ̀ rí tí wọn ó sì nífẹ̀ẹ́ láti lọ. Ugbódù wà ní ọ̀gangan ààlà tí ó pa apá Àríwá ìjọba ìbílẹ̀ Aniocha ní ìpínlẹ̀ Delta àti ìjọba ìbílẹ̀ Agbazilo ti ìpínlẹ̀ Ẹdó pọ̀. Èdè Ishan ni wọ́n ń sọ ní Ohordua tí ó wà ní àríwá rẹ̀ bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n ń sọ èdè Igbo ní Onicha-Ukwu tí ó wà ní gúsú rẹ̀. Bákan náà, èdè Igbo ni wọ́n ń sọ ní Idumuje tí ó wà ní ìwọ̀-oòrùn rẹ̀ tí wọ́n sì ń sọ Olùkùmi ní Ukwu-Nzu tí ó wà ní ìlà-oòrùn rẹ̀. Ẹ̀yí ni a fi àtẹ-onígi ṣe àlàyé rẹ̀ yìí:




*Ugbódù àti àwọn alámùúlégbè rẹ̀*

## *Ìpín-sí-sọ̀rí Asọ̀bátan*

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè tí ó dá wà gédéńgbé ní abẹ́ *Edekiri* (Yorùbá & Itsekiri) tí ó wà lábẹ́ ìsọ̀rí *Yoruboid* nínú mọ̀lẹ́bí *Niger–Congo* ni Lewis (2015) pín Olùkùmi sí nínú àtẹ Ìpín-sí-sọ̀rí Asọ̀bátan, nínú iṣẹ́ yìí, ẹ̀ka-èdè Yorùbá ni a kà á sí nípa fífi ojú àbùdá ajẹmọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wò ó. Lóòótọ́ ni a kò mọ ojúdàá iye àwọn tí wọ́n ń sọ èdè yìí báyìí, àmọ́, àjọ tí ó ń rí sí ètò ìkànìyàn nílẹ̀ Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bí ó ti jáde ní ọdún 2006 jẹ́ kí ó yé wa pé iye àwọn tí wọ́n ń sọ ọ́ jẹ́ ẹgbàáje-dín-igba-lé-láàdọ́ta (13,750).

## Àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ lórí àtúnpín sísọ̀rí ẹ̀ka-èdè Yorùbá

Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn onímọ̀ èdè Yorùbá bíi Délànọ̀ (1958), Adétúgbọ̀ (1967; 1982), Oyèláràn (1976), Akínkúgbé (1976; 1978), Awóbùlúyì (1998), Ajongolo (2005) àti Adéníyì (2005) ni wọ́n ti lo oríṣiríṣi àbùdá láti pín àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ìsọ̀rí. Lára wọn ni a ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ nísàlẹ̀ yìí.

Àtòjọ ti Délànọ̀ (1958) yìí kò gùn lé àbùdá kan pàtó bẹ́ẹ̀ sì ni kò ṣe àkóónú gbogbo ẹ̀ka-èdè tí ó wà láwùjọ Yorùbá. Adétúgbọ̀ (1967) lo òṣùwọ̀n orírun àti ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè láti pín àwọn agbègbè tí a ti ń sọ Yorùbá ní orílẹ̀-èdè Nàìjìríà sí mẹ́ta:

(i) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (NWY): Ọ̀yọ́, Ìbàdàn àti Ọ̀ṣun;

(ii) Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (SEY): Rẹ́mọ, Òndó, Ìkálẹ̀, Ọ̀wọ̀ àti Ìkàrẹ́;

(iii) Ààrin Gbùngbùn Yorùbá (CY): Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà àti Èkìtì.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ ẹ̀ka-èdè Yorùbá ni kò fojú hàn nínú iṣẹ́ yìí bíi Èkó, Ẹ̀gbá, Ìgbómìnà, Ìbọ̀lọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, síbẹ̀ ó yẹ kí á lù u lọ́gọ ẹnu torí òun ni akitiyan àkọ́kọ́ láti pín àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá sísọ̀rí. Ẹni tí ó sì sebẹ̀ àtẹ́ tí a ní kí òòṣà ó pa á, ẹni tí kò sè rárá ńkọ́?

Ní ọdún 1976 ni Oyèláràn fi ojú ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin bí àwọn olùsọ ẹ̀ka-èdè Yorùbá ṣe ń sọ ọ́ pín èdè náà sí ìsọ̀rí mẹ́rin:

(i) Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (WY): Ọ̀yọ́, Ìbàdàn, Ẹ̀gbá, Ọ̀họ̀rí-Ìfọ̀hìn; àti àwọn tí wọ́n ń sọ ní ÒkèÒgùn – Ṣakí, Ìjìó, Kétu, Sábẹ̀ẹ́; àwọn tó kù sì jẹ́ èyí tí à ń sọ ní ilẹ̀ olómìnira Benin àti Togo-Ifẹ̀ (Togo), Idáìsà, Mànígrì;

(ii) Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (SEY): Òǹdó, Ọ̀wọ̀, Ìjẹ̀bú, Ìkálẹ̀ àti Ìlàjẹ;

(iii) Ààrin Gbùngbùn Yorùbá (CY): Ilé-Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà àti Èkìtì;

(iv) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (NWY): Ìgbómìnà, Kákáñdá, Ìbọ̀lọ́, Jùmú, Bùnú, Ọ̀wọ́rọ̀, Owé àti Ẹ̀gbẹ̀.

Akinkugbe (1978) ṣe àtúnpin sísọ̀rí ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí márùn-ún:

(i) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (NWY) – Àwórì, Ẹgbá, Ẹ̀gbádò, Ọ̀yọ́, Òñkò, Ìgbómìnà;

(ii) Àríwá Ìlà-Oòrùn Yorùbá (NEY) – Ìyàgbà, Gbẹdẹ, Ìjùmú, Ikìrì, Ọwọ́rọ̀, Owé;

(iii) Ààrin GbùngbùnYorùbá(CY) – Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Àkúrẹ́, Èkìtì;

(iv) Gúsù Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (SWY) – Sábẹ̀ẹ́, Kétu;

(v) Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (SEY) – Ìjẹ̀bú, Ìlàjẹ, Ìkálẹ̀, Òǹdó, Ọ̀wọ̀.

Ogún ọdún lẹ́yìn iṣẹ́ Akinkugbe yìí ni Awóbùlúyì gbé tirẹ̀ jáde. Awóbùlúyì (1998) fi ìpele ìró èdè, ìpele ọ̀rọ̀ písọ, ìsọrí ọ̀rọ̀ àti pàtàkì ẹ̀ka-èdè sí iṣẹ́ ìwádìí lápapọ̀ pín àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ìsọ̀rí márùn-ún:

(i) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá Yorùbá (NWY) – Èkó, Àwórì, Ẹ̀gbádò, Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Òñkò, Ìbọ̀lọ́, Ìgbómìnà;

(ii) Àríwá Ìlà-Oòrùn Yorùbá Yorùbá (NEY) – Ìyàgbà, Ìjùmú, Ọ̀wọ́rọ̀, Owé;

(iii) Ààrin Gbùngbùn Yorùbá (CY) – Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì àti Mọ̀bà;

(iv) Gúsù Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (SWY) – Sábẹ̀ẹ́-Kétu (Anago) àti Ifẹ̀ (Togo);

(v) Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (SEY) – Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú, Ìlàjẹ, Ìkálẹ̀, Òǹdó, Ọ̀wọ̀, Ọ̀bà-Ìkárẹ̀.

Iṣẹ́ Awóbùlúyì (1998) yìí ṣe àfikún sí àwọn ẹ̀ka-èdè tí ó jẹyọ lábẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan nínú iṣẹ́ ìṣáájú. Bí àpẹẹrẹ, fifi Mọ̀bà kún

(CY), Ifẹ̀ (Togo) kún (SWY) àti fifi Ẹgbá ati Ọbà-Ìkàrẹ́ kún (SEY).

Adéníyì (2005) ni iṣẹ́ mìíràn tí a gbé yẹ̀wò lórí ìpín sísọ̀rí ẹ̀ka-èdè Yorùbá. Iṣẹ́ yìí pín ẹ̀ka-èdè Yorùbá sí ìsọ̀rí méje nípa lílo agbègbè tí a ti ń sọ ẹ̀ka-èdè náà, gírámà àti òdiwọn àgbọ́yé tí ó wà láàrin wọn.

(i) Ìlà-Oòrùn Yorùbá (EY) – gbogbo ẹ̀ka-èdè Àkókó, Àhọn àti Ìdó-àní;
(ii) Àríwá Ìlà-Oòrùn Yorùbá (NEY) – Ìyàgbà, Ìjùmú, Owé, Ọwọ́rọ̀, Gbẹdẹ, Ìkìri, Bùnú, Àyèré (Okun Yorùbá);
(iii) Ààrin Gbùngbùn Yorùbá (CY) – Ifẹ̀, Ìjẹ̀ṣà, Èkìtì, Àkúrẹ́, Mọ̀bà;
(iv) Gúsù Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (SWY) – Èkó, Àwórì, Ẹ̀gbá, Yewa;
(v) Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (WY) – Ànàgó, Kétu, Ifẹ̀, (Togo), Ọ̀họ̀rí, Tsabẹ ;
(vi) Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá (SEY) – Ìjẹbú, Ìlàjẹ, Ìkálẹ̀, Òǹdó, Ọ̀wọ̀, Ìjó (Àpóì);
(vii) Àríwá Ìwọ̀-Oòrùn Yorùbá (NWY) – Ọ̀yọ́, Òǹkò, Ọṣun, Ìbọ̀lọ́, Ìgbómìnà.

Ní àfikún, Ajọngọlọ (2005) fi ẹ̀ka-èdè Ào (tí à ń sọ ní àwọn agbègbè bíi; Ìfira, Ìdógún, Àfò-Ikún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) kún àwọn tí wọ́n wà ní ìsọ̀rí SEY. Bákan náà, Fábùnmi (2006) fi Mọ̀fọ̀lí (tí à ń sọ ní ilẹ̀ olómìnira Bìnì) kún ẹ̀ka-èdè tí ó wà ní abẹ́ ìsọ̀rí SWY. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, kò sí ọ̀kan nínú iṣẹ́ tí ó ti wà

ṣáájú, tí ó rí Olùkùmi gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka-èdè Yorùbá débi tí wọ́n ó pín in sísọ̀rí tí ó yẹ. Èyí sì ni èròǹgbà iṣẹ́ yìí.

## Ìpín-Sísọ̀rí Olùkùmi

Nípa lílo òṣùwọ̀n ìtàn orírun àti àbùdá ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè nínú iṣẹ́ yìí, a pín Olùkùmi sí abẹ́ ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí wọ́n ń sọ ní Gúsù Ìlà-Oòrùn Yorùbá tí a mọ̀ sí *South East Yorùbá* (SEY), ní ìbákẹ́gbẹ́ pẹ̀lú àwọn èdè bíi; Ìjẹbú, Ìlàjẹ, Ìkálẹ̀, Òǹdó, Ọwọ̀, Ào àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú, èròǹgbà iṣẹ́ yìí kì í ṣe láti yí ìhà tí àwọn elédè yìí kọ sí èdè wọn padà àbí láti jẹ́ kí wọ́n gbà dandan pé ẹ̀ka-èdè Yorùbá ni èdè tí àwọn ń sọ. Ohun tí ó jẹ wá lógún ni ṣíṣe àfihàn èdè náà nípa sísọ ìsọ̀rí tí ó bá tan tí a bá fi ojú àbùdá ajẹmọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wò ó.

### *Òṣùwọ̀n kìíní: Lílo ìtàn orírun fún pínpín*

Kò sí àkọsílẹ̀ lórí ìtàn orírun Ugbódù gẹ́gẹ́ bí kò ṣe sí fún ọ̀pọ̀ ìlú ní ilẹ̀ adúláwọ̀. Àmọ́, ìtàn àtẹnudẹ́nu tí a rí mú bọ̀ láti oko ìwádìí náà tó ṣe iṣẹ́ lé lórí. Gẹ́gẹ́ bí ìtàn ẹ̀yà Yorùbá lápapọ̀ ṣe ní oríṣiríṣi ẹ̀dà, bẹ́ẹ̀ ni ìtàn orírun ẹ̀ka-ẹ̀yà Yorùbá náà ni, èyí tí kò yọ Olùkùmi sílẹ̀. Ìtàn àtẹnudẹ́nu bí ọ̀rọ̀ òkèèrè ni ó rí. Ṣé bí kò bá lé kan, a sì dín ọ̀kan. Èyí ni ó mú Oguntomisin (1986) sọ pé;

> ...most oral traditions are prone to romanticism, conscious falsification for political reasons, and unconscious distortion of history due to memory lapse. However, these limitations do not render them useless since no source of history is entirely flawless.

> …ọ̀pọ̀ ìtàn àtẹnudẹ́nu ni ó máa ń kún fún ìṣẹ̀lẹ̀ mérìíírí, àkanlẹ̀ túnrọ nitorí ọ̀rọ̀-òṣèlú, àti àyídà ìtàn tí a kò fọkànsí látàrí ìgbàgbé. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, àwọn àkùdé yìí kò ní kí wọ́n má wúlò níwọ̀n ìgbà tí kò sí ìtàn àtẹnudẹ́nu kan tí kò ní àbàwọ́n.

Ìtàn orírun mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a rí mú bọ̀ láti oko ìwádìí yìí àmọ́ ìtàkùn tó sagbè, tó sogbá náà ni ó so elégédé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta nítorí, mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ilẹ̀ Yorùbá, pàápàá jùlọ ìpínlẹ̀ Òǹdó ní àwọn ti wá tẹ ibi tí àwọn wà ní ìpínlẹ̀ Delta lónìí dó.

Àwọn ọ̀wọ́ kan gẹ́gẹ́ bí a ti gbà á kalẹ̀ lẹ́nu Ọlọ́zà ìlú Ugbódù, Ayọ̀ Isinyemeze sọ pé agbègbè Ọ̀wọ̀ ní ìpínlẹ̀ Òǹdó ni àwọ́n ti ṣí kúrò láàrin sẹ́ńtúrì kẹsàn-án sí ìkọkànlá láti lọ tẹ̀dó sí ilẹ̀ Ibìní ní ìgbà ayé ọba Ògìso. Ìṣẹ̀lẹ̀ kàyééfì tí ó ṣẹ̀ ni ó fa ìṣí kúrò àwọn èèyàn yìí ní ìlú náà. Nígbà tí ọ̀kan nínú àwọn olorì bí àrólé, àṣẹ kí wọ́n pa àrólé ọba náà kí ìlú lè tùbà tùṣe ni ó jáde bí Olúáwo ti gbéfá janlẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, níkẹyìn, adìyẹ ni wọ́n pa dípò ọmọ náà, ọkàn àwọn ènìyàn yìí ti ṣí torí wọ́n wòye pé, 'ohun tí ó bà mú wọn pa irú àṣẹ bẹ́ẹ̀ lórí àrólé ọba, kí ni wọn kò ní lè ṣe lórí àjòjì tó wà ní ààrin wọn?' Ṣe Yorùbá sì bọ̀, wọ́n ní, 'Imí gíníngín létí àwo gbẹ̀gìrì, bójú bá kúrò níbẹ̀, ọkàn kò ní kúrò'. Èyí ni ó mú wọn wá kún ìrìn ẹsẹ̀ wọn, tí wọ́n fi dé ìlú Ewohimi tí wọ́n ti ń sọ èdè Ishan ní ìpínlẹ̀ Ẹdo. Èdè àìyedè tí ó ń wáyé ní ìlú yìí ni ó tún mú wọn tẹ̀ síwájú tí wọ́n fi doríkọ apá ilà-oòrùn. Wọ́n kọjá ìlú tí à ń pè ní Ohordua kí wọ́n tó tẹ̀dó sí ibi tí wọ́n wà

lónìí. Nítorí wọ́n ri pé ibi tí wọ́n fìkàlẹ̀ sí yìí dára fún iṣẹ́ ọ̀gbìn ó sì gbà wọ́n dáadáa ni ó mú wọn sọ ibẹ̀ ní Ugbódùmílà èyí tí wọ́n gé kúrú sí Ugbódù gẹ́gẹ́ bí a ti mọ ìlú náà lónìí.

Ọ̀wọ́ kejì, gẹ́gẹ́ bí olóògbé olóyè H.T. Temofẹ́ ṣe sọ, gbà pé Àkúrẹ́ àti Ọwọ̀ ni àwọn tí wọ́n tẹ Ugbódù dó ti ṣí wá. Wọ́n ní, ìran mẹ́ta nínú ìran mẹ́rin tí ó wà ní Ugbódù wá láti Àkúrẹ́: Kòkòrò àti Àgbá tí wọ́n jẹ́ ọmọ-ìyá pẹ̀lú ọbàkan wọn Igwisí. Nínú ìrìnàjò wọn, wọ́n gba Ẹdo àti Ohordua kí wọ́n tó dé ibi odò kan tí wọ́n ń pé ní Odù. Wọ́n fo odò yìí kọjá wọ́n sì tẹ̀dó síbi tí wọ́n pè ní ugbó-Odù. Nítorí àkọlù lóòrèkóòrè, wọ́n ní láti tẹ̀síwájú nínú ìrìnàjò wọn. Wọ́n la odò mìíràn tí a mọ̀ sí Ọhẹ́ kọjá wọ́n sì tẹ̀dó sí ibi tí wọ́n wà lónìí. Síbẹ̀, àwọn alákọlù yìí kò dẹ̀yìn. Lẹ́yìn ìgbà díẹ̀, babaláwo kan wá da ara pọ̀ mọ́ wọn láti ìlú Ọwọ̀. Nígbà tí ó rí àìbalẹ̀ ọkàn tí àwọn alákọlù yìí ń fà ní ìlú náà, ó padà sí Ọwọ̀ láti lọ kó àwọn jagunjagun wá, wọ́n sì fìkàlẹ̀ sí ìtòsí odò tí àwọn alákọlù náà máa ń gbà wọlé, gẹ́gẹ́ bí olùdáàbòbò. Lóòótọ́, wọ́n fi òpin sí àkọlù tí ó máa ń wáyé lemọ́lemọ́ náà. Èyí ni ó sì di ìran kẹrin tí ó wà ní Ugbódù lónìí.

Ohun tí ọ̀wọ́ kẹta gẹ́gẹ́ bí a ti ri kà nínú Ugbelase (1992) sọ ni pé, Àkúrẹ́ nìkan ni àwọn ará Ugbódù ti ṣí wá tẹ̀dó sí ibi tí wọ́n wà lónìí.

## ***Ìfojú lámèétọ́ wo àwọn ìtàn orírun náà***

Lóòótọ́, Ugbódù kan ṣoṣo ni à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ ṣùgbọ́n ìtàn mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a rí mú bọ̀ láti oko ìwádìí. Èyí ni yóò mú wa fi ojú lámèétọ́ wo àwọn ìtàn náà.

Àgbéyẹ̀wó àwọn ìtàn náà fi yé wa pé, bí ó ti lè wù kí á fara mọ́ ìtàn orírun Ugbódù bí Ọlọ́zà ṣe sọ ọ́, kò tọnà kí á kó ti olóògbé Temofẹ́ dànù torí àgbà májẹ̀ẹ́-ó-bà-jẹ́ nínú èdè àti àṣà ni àwọn náà nígbà ayé wọn. Yàtọ̀ sí ìtàn àtẹnudẹ́nu wọ̀nyí, àwọn onímọ̀ kan tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí èdè yìí sọ pé Àkúrẹ ni wọ́n ti wá (Ugbelase, 1992 ) tí àwọn mìíràn sì sọ pé Ọwọ̀ ni wọ́n ti wá (Arokoyo, 2012; Awogu, 2002; Eleshin, 2016; Obisesan, 2012). Èyí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìpínlẹ̀ Òǹdó ni wọ́n ti ṣí. Pẹ̀lú gbogbo àwọn ẹ̀rí yìí, ó ṣe é ṣe láti gbàgbọ́ pé ìlú Ọwọ̀ nìkan tàbí Ọwọ̀ àti Àkúrẹ́ ni wọ́n ti ṣí, àmọ́ yóò nira láti gbàgbọ́ pé ìlú Àkúrẹ́ nìkan ni wọ́n ti ṣí kúrò.

Ní àfikún, bí a bá wo orúkọ olórí ìlú náà tí í ṣe Ọlọ́zà, a ó fẹ́ fi ara mọ́ ọ̀wọ́ tí ó ní ìlú Ọwọ̀ ni àwọn ti ṣí, nítorí orúkọ náà wà ní ìbámu pẹ̀lú ti olórí ìlú Ọwọ̀ tí í ṣe Ọlọ́wọ̀ yàtọ̀ sí ti ìlú Àkúrẹ́ tí í ṣe Déjì. Èrò ti wa ni pé, kí àwọn àrá Ugbódù lè máa rántí orírun wọn ni wọ́n ṣe ṣẹ̀dá orúkọ olórí wọn ní ìlànà ti ìlú Ọ̀wọ̀. Bákan náà, orúkọ náà (Ọlọ́zà) jẹ́rìí sí àlàyé wa wí pé ìran Yorùbá ni àwọn tí wọ́n ń sọ Olùkùmi torí pé *oní* **+***orúkọ ìlú* ni Yorùbá fi ń ṣẹ̀dá orúkọ ọba wọn ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Bí àpẹẹrẹ; Ọlọ́jà ni Ẹpẹ́, Olúbàdàn ti Ìbàdàn, Ọlọ́fà ti Ọ̀fà, Aláke ti Ẹgbá, Olówu ti Òwu àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ jẹ́ kí a wo ìgbésẹ̀ mofọ́lọ́jì ìṣẹ̀dá orúkọ tí ó wà ní (1).

| | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. | i. | Oní | + | ọzà | ⟶ | Ọlọ́zà |
| | ii. | Oní | + | ọjà | ⟶ | Ọlọ́jà |
| | iii. | Oní | + | Ọ̀wọ̀ | ⟶ | Ọlọ́wọ̀ |

Yàtọ̀ sí pípàrọ̀ *w* inú Ọlọ́wọ̀ àti *j* inú Ọlọ́jà si *z* nínú Ọlọ́zà, bákan ni ìhun wọn. Ní kúkúrú èdè, ìgbésẹ̀ mọfọ́lọ́jì kan náà ni a fi ṣẹ̀dá wọn nípa lílo àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ *oní-* mọ́ ọ̀rọ̀ ìpìlẹ̀ *ọzà, ọjà* àti *ọ̀wọ̀*.

### *Ọ̀ṣùwọ̀n kejì: Ẹ̀rí fún àwíjàre ìpín nípa àbùdá ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè*

Yàtọ̀ sí ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin ìtàn orírun Olùkùmi àti Yorùbá, tí a bá wo àbùdá ajẹmọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè rẹ̀, a ó ri pé ó wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ohun tí Awobuluyi (1998) tò jọ pé ó pa àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí wọ́n ń sọ ní gúsù-ilà-oòrùn Yorùbá (SEY) pọ̀. Bí àpẹẹrẹ, ṣíṣàmúlò àwọn ìro kan tí kò sí nínú Yorùbá àjùmọ̀lò, kí á bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ pẹ̀lú fáwẹ́lì [u], níní orúkọ kan náà fún àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ kan tí ó yàtọ̀ sí bí ẹ̀yà Yorùbá yòókù ṣe ń pè wọ́n, bí a ṣe ń ṣẹ̀dá gbólóhùn àyísódì tí ó ní ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ nínú, bí a ṣe ń ṣẹ̀dá gbólóhùn ìbéèrè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Olùkùmi tún fi ìró fáwẹ́lì jọ Ìjẹ̀ṣà àti Irùn (Èkìtì) tí wọ́n jẹ́ Yorùbá ààrin gbùngbùn (CY) tí ó ní ìró fáwẹ́lì àìránmúpè mẹ́sàn-án àti àránmúpè méje, níbi tí a ti rí [ɩ], [ʊ], [ɩ̃] àti [ʊ̃]. Àtiwáyé orúkọ ìlú àti orúkọ ọba ìlú náà sì tún fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹ̀ka-èdè Yorùbá ni.

Ọ̀kan lára ìdí pàtàkì tí a fi gbà pé ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí ó wà ní abẹ́ ọ̀wọ́ SEY ni Olùkùmi ni pé, ìró kọ́nsónáǹtì tí ó ní

ju ti Yorùbá àjùmọ̀lò lọ. Láfikún ìró méjìdínlógún tí Yorùbá àjùmọ̀lò ní, Olùkùmi tún ní Kọ́nsónáǹtì Akùnyùn Afèrìgìpè Afúnnupè [z], Kọ́nsónáǹtì Akùnyùn Afàfàsépè Afúnnupè [ɣ], Kọ́nsónáǹtì Àìkùnyùn Afàfàsépè-Ajẹmétè Àsénupè [kʷ], Kọ́nsónáǹtì Akùnyùn Afàfàsépè-Ajẹmétè Àsénupè [gʷ], àti Kọ́nsónáǹtì Àìkùnyùn Afàjàfèrìgìpè Àséṣí [ʧ] tí wọ́n wà nínú SEY. Àpẹẹrẹ àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tí a ti rí àwọn ìró yìí nínú Olùkùmi àti Ọ̀wọ̀ tí ó jẹ́ àpẹẹrẹ (SEY) ni a tò jọ sí (2), a sì ṣàfihàn bí irúfẹ́ ẹyọ ọ̀rọ̀ náà ṣe wà ní Yorùbá àjùmọ̀lò (SY) pẹ̀lú.

| | 2. | Olùkùmi | Ọ̀wọ̀ (SEY) | SY | Gloss |
|---|---|---|---|---|---|
| [kʷ]: | (i) | kʷọ́rọ̀ | kʷọ́rọ̀ | dákú | 'faint' |
| | (ii) | kʷálẹ̀ | kʷálẹ̀ | kúnlẹ̀ | 'knee down' |
| [gʷ]: | (i) | gʷẹ̀ | gʷẹ̀ | wẹ̀ | 'wash' |
| | (ii) | ẹ̀gʷá | ẹ̀gʷá | ẹ̀wá | 'ten' |
| [ɣ]: | (i) | aɣó | aɣó | awó | 'guinea fowl' |
| | (ii) | ẹɣẹn | ẹɣẹn | ẹyin | 'egg' |

| | Olùkùmi | | | Ọ̀wọ̀ | |
|---|---|---|---|---|---|
| [ʧ]: | (i) | uʧín | 'greet' | (i) iʧu | 'yam' |
| | | | | (ii) ʧe | 'make' |

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé [z] kò sí nínú èdè Ọ̀wọ̀, ó wà nínú àwọn èdè SEY mìíràn bíi Ào. Àwọn àpẹẹrẹ tí a tò sábẹ́ èdè Ào yìí jẹ èyí tí a rí nínú Taiwo (2006).

| | Olùkùmi | | Ào (SEY) | |
|---|---|---|---|---|
| [z]: | (i) zẹ | 'eat' | (i) zẹ | 'eat' |
| | (ii) ọlọ́zà | 'king' | (ii) iízẹ | 'yam' |

Ẹ̀rí mìíràn láti fihàn pé SEY ni Olùkùmi ni wí pé, a lè bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ pẹ̀lú fáwẹ́lì [u] nínú rẹ̀ bi ti SEY tó kù. Àtòjọ àpẹẹrẹ tí ó wà ní (3) fi ìdí èyí múlẹ̀ níbi tí a ti gbé e sí ẹ̀gbẹ́ Ọ̀wọ̀ tí ó jẹ́ àpẹẹrẹ SEY àti Yorùbá àjùmọ̀lò (SY).

| 3. | Olùkùmi | Ọ̀wọ̀ (SEY) | SY | Gloss |
|---|---|---|---|---|
| i. | ulé | ulí | ilé | 'house' |
| ii. | ugún | ugún | igún | 'vulture' |
| iii. | ùgbẹ́n | ùgbẹ́n | ìgbín | 'snail' |
| iv. | uná | uná | iná | 'fire' |
| v. | urẹn | urin | irin | 'iron' |

Olùkùmi tún ní àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí wọ́n wà ní ìbámu pẹ̀lú bí wọ́n ṣe ń pè wọ́n nínú SEY yàtọ̀ sí ti ẹ̀ka-èdè tó kù bí o ṣe hàn ní (4).

| 4. | Olùkùmi | Ọ̀wọ̀ (SEY) | SY | Gloss |
|---|---|---|---|---|
| i. | gede[2] | gede | gbogbo | 'all' |
| ii. | iwín | iwín | imí/ìgbẹ́ | 'feaces' |
| iii. | ohun | ohun | iyọ̀ | 'salt' |

[2] 'Kete' ni wọ́n ń lò ní ilẹ̀ Èkìtì (CY) nígbà tí Ìjẹ̀bú ń lo 'dede' fún ẹyọ-ọ̀rọ̀ kan náà. Méjèèjì yìí ṣì súnmọ́ 'gede' ju 'gbogbo' ti ẹ̀yà Yorùbá yòókù ń lò lọ.

| | | | |
|---|---|---|---|
| iv. ita | ita | ata | 'pepper' |
| v. alẹ̀ | alẹ̀ | ilẹ̀ | 'ground' |
| vi. eghìhò | èghìghò | èéfín[3] | 'smoke' |
| vii. ẹlá | ẹlá | màlúù | 'cow' |

Wíwọ́pọ̀ fáwẹ́lì [ẹn] nínú Olùkùmi bi ti SEY, yàtọ̀ sí ti Yorùbá àjùmọ̀lò tí a ti rí ẹ̀ta-hóró bíi ìyẹn, hẹn àti hẹ́hẹ̀n náà jẹ́ ìdí mìíràn pàtàkì tí a fi pín in sí abẹ́ SEY. Àpẹẹrẹ (5) jẹ́ ẹ̀rí máa jẹ́ mi nìṣó àkíyèsí yìí.

5.

| Olùkùmi | Ọ̀wọ̀ (SEY) | SY | Gloss |
|---|---|---|---|
| i. ẹmùrẹ́n | amùrẹ́n | aláǹgbá | 'house' |
| ii. ẹghẹn | ẹghẹn | ẹyin | 'egg' |
| iii. ùgbẹ́n | ùgbẹ́n | ìgbín | 'snail' |
| iv. pẹ́n | pẹ́n | pín | 'split' |
| v. gbẹ̀n | gbẹ̀n | gbìn | 'plant' |

Bí orúkọ ìlú náà ṣe wáyé fihàn pé ẹ̀ka-èdè Yorùbá ni. Lẹ́yìn gbogbo ohun tí ojú wọn rí nínú ìrìnàjò wọn, nígbà tí wọ́n dé ibi tí wọ́n wà lónìí, tí wọ́n sì ri pé ibẹ̀ dára fún nǹkan ọ̀gbìn, ṣé Yorùbá ní'Bí ebi bá kúrò nínú ìṣẹ́, ìṣẹ́ bùṣe' èyí ni ó mú wọn sọ ìlú náà ní Ugbódùmílà. A ṣẹ̀dá orúkọ yìí pẹ̀lú ìgbésẹ̀ mofọ́lọ́jì tí a mọ̀ sí àkànpọ̀ àti àgékúrú. Odidi gbólóhùn bí ó ti hàn ní (6) ni a sọ di ẹyọ ọ̀rọ̀, èyí tí a gé kúrú sí bí ó ti wà lónìí kí ó lè rọrùn ní pípé.

[3] Èfínfín ni ọ̀rọ̀ ìpilẹ̀ yìí kí ìgbésẹ̀ fonọ́lọ́jì tí a mọ̀ sí àrànmọ́ tó sọ ọ́ di èéfín.

6. Ugbó dù mí là. ⟶ Ugbódùmílà ⟶ Ugbódù
   Bush save 1sg be-rich
   'Bush saved and enriched me.'

Yàtọ̀ sí ẹ̀rí fonọ́lọ́jì, ẹyọ ọ̀rọ̀ àti mofọ́lọ́jì láti fi hàn pé abẹ́ ìsọ̀rí SEY ni Olùkùmi wà, ìpele síntààsì rẹ̀ náà fi ìdí èyí múlẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, gbólóhùn àyísódì tí ó ní ọ̀rọ̀ arọ́pó orúkọ nípò olùwà. Yàtọ̀ sí atọ́ka àyísodi inú gbólóhùn àyísódì, ìrísí àwọn ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ máa ń yí láti bá ìyísódì mu ní ìbámu pẹ̀lú bí ó ṣe ń wáyé ní SEY bí Ọwọ̀ àti Ào. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ (7-12), níbi tí abala (b) ti jẹ́ àyísódì fún abala (a).

Olùkùmi

| | |
|---|---|
| 7. (a) Mà á yú ni. | (b) Mí a yú. |
| 1Sg. Fut. go AFF | 1Sg-Neg Fut-Neg go |
| 'I will go.' | 'I will not go.' |
| 8. (a) Á yà yú ni. | (b) É a yà yú. |
| 3sg aux go AFF | 3sg-Neg Neg aux go |
| 'S/He can go.' | 'S/He can not go.' |
| 9. (a) Mì í wa ni. | (b) Mí i wa. |
| 1Sg. Prog. come AFF | 1Sg-Neg Fut-Neg come |
| 'I am coming.' | 'I am not coming.' |

Ọ̀wọ̀

| | |
|---|---|
| 10. (a) Mà á yú. | (b) Mí ì yú. |
| 1Sg. Fut. go | 1Sg-Neg Fut-Neg go |

'I will go.' 'I will not go.'

11. (a) Ó yà kare/yú. (b) É è yà yú.
3sg aux go 3sg-Neg Neg aux go
'S/He can go.' 'S/He can not go.'

12. (a) Mì í wa. (b) Mí ì ní wá.
1Sg. Prog. come 1Sg-Neg Fut-Neg be come
'I am coming.' 'I am not coming.'

Ní àfikún sí atọ́ka ìyísódì tí ó wà ní abala (b), a ri wí pé àwọn ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ inú àwọn gbólóhùn àyísódì yìí yàtọ̀ sí ti inú gbólóhùn ìjẹ́hẹn tí ó wà ní abala (a). Nínú Olùkùmi, *Mà* paradà sí *mí*, *á* di *é* bẹ́ẹ̀ sì ni *mì* di *mí*, bí *mà* ti yí sí *mí* tí *ó* yí sí *é* tí *mì* sì di *mí*, nínú Ọ̀wọ̀. A rí òye pé àmì ohùn òkè ni àwọn ọ̀rọ̀ arọ́pò-orúkọ wọ̀nyí ní nínú gbólóhùn àyísódì tí wọ́n sì lè jẹ́ àmì ohùn ìsàlẹ̀ tàbí tòkè nínú gbólóhùn ìjẹ́hẹn. A rí ẹ̀rún *ni* tí Ajíkòbi (2017) pè ní atọ́ka ìjẹ́hẹn ní ìgbẹ̀yin gbólóhùn ìjẹ́hẹn Olùkùmi, èyí tí kò sí nínú gbólóhùn àyísódì, nítorí ìdàkejì ìjẹ́hẹn ni ìyísódì jẹ́.

Ẹ̀rí ajẹmọ́-síńtààsì mìíràn tí a fi pín Olùkùmi sí abẹ́ ìsọ̀rí SEY ni bí a ṣe ń ṣẹ̀dá gbólóhùn ìbéèrè oní-ìdáhùn-gígùn nínú èdè náà. Ọ̀nà tí à ń gbà ṣẹ̀dá irúfẹ́ gbólóhùn yìí nínú Olùkùmi yàtọ̀ sí bí a ṣe ń ṣẹ̀dá rẹ̀ nínú Yorùbá àjùmọ̀lò tàbí àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá mìíràn nípa pé ìlò atọ́ka *ni* tí ó máa ń tẹ̀lé ẹ̀rún aṣèbéèrè kì í sí fún òun. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú bí ẹ̀ka-èdè tí ó wà ní abẹ́ SEY bí Ọ̀wọ̀ ṣe ń ṣẹ̀dá irú ìbéèrè náà.

| Olùkùmi | Ọ̀wọ̀ |
|---|---|
| 13. (i) Kí orúkọ rẹ? | 14. (i) Kí orúkọ rẹ? |
| QM name 2sg | QM name 2sg |
| ‘What is your name?’ | ‘What is your name?’ |
| (ii) Kàá íyà wó fẹ́ yú? | (ii) Kẹ̀ẹ́ ibi wó fẹ́ gbànrè? |
| QM place 2sg. want go | QM place 2sg. Want go |
| ‘Where do you want to go?’ | ‘Where do you want to go?’ |
| (iii) Olú eghó té ó hún ẹ? | (iii) Olú eghó ó gbé wún ẹ? |
| QM money that 3sg. give 2sg | QM money 3sg carry give 2sg |
| ‘How much did he give you?’ | ‘How much did he give you?’ |

Àlàyé àti ẹ̀rí tí a ti mú ẹnu bà nínú iṣẹ́ yìí nípa Olùkùmi ni yóò mú wa dábàá àtẹ-onígi asọ̀bátan ìsàlẹ̀ yìí láti ṣàfihàn Olùkùmi gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka-èdè Yorùbá:




*Àtẹ-onígí ìpín sísọ̀rí asọ̀bátan*

## Ìgúnlẹ̀

Bébà yìí fi hàn pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè tí ó dá wà gédéńgbé ni àwọn kan ka Olùkùmi sí, ẹ̀ka-èdè Yorùbá tí ó wà ní abẹ́ ọ̀wọ́ SEY ni bí a bá fi ojú àbùdá ajẹmọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè (bíi fonọ́lọ́jì, mofọ́lọ́jì àti síńtáàsì) àti ìtàn orírun wò ó. Àgbọ́yé tí ó wà láàrin rẹ̀ àti Yorùbá pàápàá jùlọ àwọn ẹ̀ka-èdè tí wọ́n wà ní ìsọ̀rí SEY pọ̀ ju ohun tí ó lè yà wọ́n sọ́tọ̀ lọ. Ìpínlẹ̀ Delta ní gúsù-ilà-oòrùn Nàìjíríà ni wọ́n ti ń sọ ọ́ láàrin àwọn Igbo nígbà tí àwọn ẹ̀ka-èdè Yorùbá yòókù forí pitẹ́ sí gúsù-ìwọ̀-oòrùn Nàìjíríà. Ìwádìí yìí jẹ́ kí ó yé wa pé, bí ó ti wù kí èdè méjì tí wọ́n ní orírun kan náà ti pínyà pẹ́ tàbí jìnnà síra sí, àgbọ́yé tí yóò fi wọ́n hàn bí ọmọ ìyá kan yóò ṣì wà láàrin wọn.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adeniyi, H. (2005). "Àwọn Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá", In H. Adeniyi, and O. Akinloye (Eds.) *Ìlò-Èdè àti Ẹ̀ka-Èdè*. Trenton: African Press.

Adetugbo, A. (1967). The Yoruba language in Western Nigeria: Its Major Dialect Areas. Unpublished Ph.D. Thesis, University of Columbia.

Adetugbo, A. (1982). Towards a Yoruba Dialectology, in A. Afolayan (ed.) *Yoruba Language and Literature*. Ibadan: University Press Ltd and University of Ife Press, pp 202-224

Ajikobi, A.E. (2017). 'The Status of Particle '*NI*' in Olùkùmi', in *JOLAN: Journal of the Linguistic Association of Nigeria,* volume 20, number 2 pp 45-51.

Ajongolo, P.O. (2005). "Negation in the Ào Dialect of Yoruba". Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ibadan, Ibadan, Nigeria.

Akinkugbe, O. (1976). 'An Internal Classification of the Yoruboid group (Yoruba, Isekiri, Igala)', *Journal of West African Languages,* volume xi, number 1-2: 1-19.

Akinkugbe, O. (1978). A Comparative Phonology of Yoruba Dialects, Isekiri, and Igala. Unpublished Ph.D. dissertation, University of Ibadan, Ibadan.

Arokoyo, B.E. (2012). A Comparative Phonology of the Olùkùmi, Igálà, Owé and Yorùbá Languages. Towards Proto-Niger Congo: Comparison and Reconstruction, Paris 18-21

Awobuluyi, O. (1998). "Àwọn Ẹ̀ka-Èdè Yorùbá", Paper Read at Yoruba Studies Association of Nigeria, Pastoral Institute, Ibadan.

Awogu, M.A. (2002). Olukumi- A Melting-Pot of Yoruba and Igbo? Unpublished B.A Thesis, University of Benin, Benin City.

Ayeomoni, O. M. (2012). ''A Lexico-Syntactic Comparative Analysis of Ondo and Ikale dialects of the Yoruba Language. *Theory and Practice in Language Studies*, Vol. 2, No. 9, pp. 1802-1810. Finland: Academy Publishers.

Chambers, J. K. and Trudgill, P. (1998). *Dialectology* (2nd edition) Cambridge: CUP.

Delano, I. O. (1958). *Atúmọ̀ Èdè Yorùbá*. London: Oxford University Press.

Edward, J.V. (2010). Dialectology. (Linguistics 201). Online version: http://pandora.cii.wwu.edu/vajda/ling201/test3materials/dialectology.htm Retrieved on 3/24/2010

Fabunmi, F. (2006). Tense and Aspect in Mọ̀fọ̀lí Dialect of Yorùbá", Unpublished Ph.D. Thesis, Obafemi Awolowo University, Ile-Ife.

Issa, O. S. & Eleshin, A.F. (2016). Comparative Analysis of Question Formation in Olùkùmi and Standard Yorùbá: A Minimalist Approach. *Drumspeak: International Journal of Research in the Humanities, Faculty of Arts, University of Cape Coast, Ghana,* Vol. 5, No. 2 pp 78-100.

Lewis, M.P., Gary F.S. & Charles D.F (eds.), (2015). Ethnologue: Languages of the World, (18th edition). DallasTex:SIL International. Online Version: http//www. Ethnologue.com/.

Maher, J. (1996). 'A cross linguistic study of language contact and language attrition'. In H.W. Selinger, and R.M. Vago (Eds.), *First language attrition*. London: Cambridge University Press.

Obisesan, H. (2012). Comparative Linguistics of Olùkùmi, Ọ̀wọ̀ and Standard Yorùbá. Unpublished M.A. Thesis, University of Ilorin, Ilorin.

Oguntomisin, G.O. (1986). *Kurunmi of Ijaye*. Lagos: John West Publications Ltd.

Olumuyiwa, T.O. (1994). *Àwọn Ẹka-èdè Yorùbá 1*. Akure: Montem Paperbacks.

Oluwadoro, J. & Abiola. A. (2016). "Olukumi: A Dialect of Yoruba in Diaspora" *Papers in English and Linguistics* (PEL) Vol. 17, No 1, pp. 320-335.

Omamor (1976). 'The Place of Itsekiri in Relation to Yorùbá' *Research Notes*. Volume 7, numbers 1-2. University of Ibadan.

Oyelaran, O. O. (1976). "Linguistics Speculations on Yoruba History" *Seminar Series No 1, Part 11.* Department of African Languages and Literatures, Obafemi Awolowo University.

Taiwo, O. (2006). *MOFỌLỌJÌ*. Ibadan: Lay of Ventures Publishing Educational Services.

Ugbelase, H.A. (1992). A Comparative Study of the Phonology and Lexicon of Olukumi and Akure dialect of Yoruba. Unpublished B.A Thesis, University of Benin, Benin City.

Wardhaugh, R. (2010). *An Introduction to Sociolinguistics* (6th edition). United Kingdom: Wiley-Blackwell